# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 861 LAGOS SARTUDAY MARCH 23rd—MARCH 29th 1963 KỌBỌ MEJI (2D)

**Eleyi Enmo:**

## Baba Kan Pa Awon Omo Re Nitori Owo Idana

NEW DELHI—Awọn ọlọpa'nu ilu India nwa ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Sohan Lal, ẹni ọdun marundilogoji ti o pa awọn ọmọbinrin mẹrin ti iyawo rẹ bi fun un kiri.

Irohin ti a gbọ nipa ọgbẹni na ni pe lọjọ ti o fẹ pa awọn ọmọge mẹrin na, o ran iya wọn ni nkan lọja, o si ti awọn arẹwa ọmọbinrin na mọ iyara o si fun wọn ni akara oni majele jẹ, gbogbo nwọn si ku lọjọ kanna.

Nwọn ni nkan ti o fa ti ọkunrin yi fi jẹ iṣẹ buruku yi fun awọn ọmọ rẹ na ni owo'idana (dowries) ti o ni on ko le ri san lori awọn ọmọge na ti nwọn ba dagba tan, ti nwọn fẹ lọ si ile ọkọ wọn.

Gẹgẹbi aṣa awọn ara ilu India, baba ọmobinrin ni o ma nsanwo idana ti ọmọ rẹ obinrin ba fẹ lọ si ile ọkọ.

Onirohin wa ni ponun mẹrin ni nwọn nsan fun baba awọn ọmọ yi nibiti o gbe nṣiṣẹ, ko si ni ọna miran ti o le gba ri owo-idana awọn ọmọge ti o bi na ni o ba fi pa wọn.

## Awon Egba Nsinku Alake Ni Abeokuta

ABẸOKUTA— Gbogbo awọn ọmọ Ẹgba ti mbẹ ni idalẹ ti bẹrẹsi'de si ilu Abẹokuta ni ana fun ti oku Ọba Alaiyeluwa Ladapọ Ademọla Keji ti nwọn fẹ sin. O di oṣu kẹta gbako nisisiyi ti Ọba na ti waja.

Ni,ana tiṣe ọjọ Jimọ ni nwọn bẹrẹsi sinku na, ti gbogbo awọn Imale ilu Ẹgba ṣe isin ati adura fun Ọba na.

Ni alẹ oni Satide ni awọn sanmọri sanmọri'a jo'ijo nla kan ni Centenary Hall ni Ake, ni owurọ ọla Sunday ni nwọn yio fi isin nla kan pari isinku na ni Ṣọṣi Ake (St Peter's).

Lẹhinti nwọn ba sinku yi tan ni awọn Ologboni ati awọn afọbaje yi to dawọle ati yan Alake miran.



Ọba Alak:

## Ìsele Pa Egberun Enia Ni Indonisia

INDONISIA — Ẹgbẹrun enia lọkunrin ati lobinrin ni a gbọ wipe iṣẹlẹ ti o ṣe ni oru ana pa ni erekusu kan ti nwọn npe ni Baali ni Indonia. Iṣẹlẹ na ba nkan jẹ pupọ fun awọn ara ilu na

## Awon Oyinbo Ri Awon Iran Tuntun Kan Ninu Igbo Guinea

NEW GUINEA—Awon Oyinbo kan ti o nṣe ọdẹ kiri inu aginju igbo ṣe alabapade awọn iran enia kan ti nwọn di ẹni-gbagbe si inu igbo ti nwọn ko mọ nkan ti o nlọ ni aiye nisisiyi, ti nwọn npe ni G'hom. Epo ara igi ni awọn ọkunrin wọn fi ṣe aṣọ; awọn obinrin wọn ki lo aran, koriko ni awọn fi ṣe aṣọ iro.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ lẹnu Olori awọn ọdẹ na, Ọgbẹni J. O Hunter, o ni bi on pẹlu awọn ẹlẹgbẹ on ti nwọ igbo kiri ni awọn ṣe alabapade awọn iran enia yi ninu aginju igbo, ẹru ba awọn na lati ri awon.

Ọgbẹni Hunter ni awọn ajoji enia na ni awọn ko bọsi ojutaiye ri, awọn ko nrin ju arin ibiti nwọn gbe gbọ ede ara wọn lọ.

(wo iyoku ni oju ewe kẹfa)

## Adajo Kan Gba Iwe Ebu Lodo Loya

IBADAN— Adajọ-agba Kotu ganran ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibadan, Ọlọla Samuel Quashie-Idun gba iwe-ebu kan lọdọ "lọya" kan ti o ni on ko lẹ da orukọ ara on.

Ninu iwe-ebu ti ọgbẹni ti o pe ara'rẹ ni "lọya" na kọ si adajọ na o bẹrẹsi sọ ikan ko jọkan ọrọ fun un. O ni alaimore enia ni adajọ na, o ni nitoripe gbogbo awọn ti nwọn ṣe alatilẹhin fun de ipo ti o de loni ni o ti fi ibi ṣu patapata.

O ni ki o mọ gbagbe wipe ko le de iru ipo ti o de loni rara ti o ba jẹ wipe Ghana ilu rẹ ni o wa. "Lọya" ti o kọwe na ni ilẹ a da fun adajọ na pẹlu awọn ọmọ ati awọn ọmọ ọmọ rẹ.

# Oko Aropileni Oba Meka Jalule

NICE—Ọkọ aropileni ti Oba ilu Meka ja lulẹ ni ijọta ni eti ilu Faranse ti nwọn npe ni Alps, gbogbo awọn enia mẹrindinlogun ti nwọn wa ninu ọkọ na ni nwọn ku bamu bamu.

Irohin gbọ ni pa jamba ti o ṣe ọkọ aropileni na ni pe Ọba Mẹka ti nwọn npe ni Saudi pẹlu awọn ọmọ lẹhin rẹ mbọ lati ilu kan ti awọn npe ni Geneva ọkọ wọn na si ti de ilu Nice nibiti yinyin gbe ti bo gbo gbo ilẹ ki o to jabọ.

Ọpọlọpọ awọn eniwe irohin ni o lọ si ọdọ Ọba na ni ile alaisan ti on na gbe wa lati gba ọrọ lẹnu rẹ. O ni jamba ọkọ na kiṣe amuwa Ọlọrun ti awọn ọmọ enia ni.

Ọba na ni ko ti ya ti on yio sọ gbogbo ọrọ jamba ti ọkọ ti o ja lulẹ na.




Facts speak for themselves. This venerable veteran a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,367,000 miles. No douth it would have gone on if Daimler-Benz AG had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last just as much now as they were then to give many years and many miles of trouble-free economical service.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTOR LTD.

LAGOS. (EB). IBADAN. KANO, KADUNA. JOS, PORT HARCOURT, ABA.

SUB-DISTRIBUTORS.

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY. ONITSHA. ABA.

## Nwon ji Kora kan gbe ni Togo

LOME—Ijọba tuntun ilu Togo ti Ọgbẹni Grunitzky nṣe alakoso rẹ lọwọ ti fi ẹsun awọn kan sun wipe nwọn ṣe nkan ti o ya awọn lẹnu, nwọn ji oyinbo Kọra kan gbe loru ọganjọ lọ si ilẹ Ghana.

Irohin ti a gbọ nipa ọrọ na ni pe Oyinbo Kọra, Joseph Haddad ti nwọn ji gbe na ti wa ni Ghana ri nibiti nwọn gbe ti ti mọle, ṣugbọn nigbati o ya nwọn da a silẹ iyawo rẹ si ni ki o ma wa ba on gbe ni Togo.

Ni oru ọjọ kan ni ni ọkunrin Kọra kan ti n njẹ Hassan Fowell tan lọ si ipinlẹ Togo ati Ghana ninu moto rẹ, ibẹ ni awọn ọlọpanu ilu Ghana ti wa a lọ si'lu wọn.

Nwọn ko ti mọ bi nwọn ti ṣe ọkunrin na si di ọjọ oni.

# Irohin Ipinle Ariwa

(Lati Owo Mallam Shewu)

## Nwon Ko Tete

Awon Olotu Ijoba Ipinle Ariwa ni Oke Oya fi kele ge awon ti o nfi ere bolu afesegba se tete at. Ni ose ti o koja ninu ile igbimo won ni Kaduna, nwon se ofin wipe enikeni ko gbodo ta tete ti nwon npe ni football pools mo lati inu osu ti mbo.

Ogunlogo awon enia ti nwon nfi Pulu (pools) yi se ise se j e u n ni nwon kowe ebe si awon Olotu Ijoba won pe ki nwon wo oro na se; nwon ni ko bosi rara nitoripe oro tete tita yi lodi si oro awon Imale.

## Ara Sokoto

Ni ijerin ni awon kansilo ilu Sokoto ati awon ti o wa ni igberiko wa ki Olola Ahmadu Bell, Olotu Ijoba Ipinle Ariwa ti o ni on ri iwe ojo-iku gba ninu ile ti Ijoba ko fun un ni Nasarawa ni Kaduna. O si dupe lowo gbogbo won wipe nwon ku ibakedun ara on.

## Banki Titun

A w o n Alakoso Ijoba Ariwa pa pa ngbero lati da ile ifowo pamo tuntun sile ni ile re nwon si ti fi owo goboyi (£2 million) kan sile fun eto yi. Alhaji Bashar tise Minister kan ni o so eyi ni ile Igbimo, o ni nibe ni awon yia ti ma ya awon egbe lowo fuu nkan ogbin won.

## Omo Dara

Awon ara Ariwa paapa fe se ere IJE Omo-dara-o-dojo ti nwon yio pe ni Miss Northern Nigeria. Nino eyi nwon je ... alariria kan ... ijejo (Sat-ide) ni Kaduna; o wa ku ti Kano, Zaria Sokoto, Katsina, Maiduguri Minna Markudi ati Jos.

Alhaji Kabir tise alaga Katagun ni yio se alaga eto na lojo ti g b o g b o awon omoge - na ba tun pade ni Kadnna.

---

Awon Iwe Asiko:

# Ede Yoruba Dun Ka

(LATI OWO AKOWE)

Gege bi mo ti se ileri fun enyin ti e nka oro mi lori awon iwe Yoruba ti nwon nte jade ni asiko ti a wa yi, mo ni ma te awon oro AŞARO die jadeninu IWE Ikilo FUN Awon Odo (apa karun) ti Alufa (Rev.) E. A. Atilade ko.Okan n yi ninu awon oro asaro inu iw e na:

MA FI IDA NA ŞE 'JAMBA

1. Owo re jaja te eku ida agbara,
O bere si fi ida na se jamba fun ota re;
Eku ida na la bo s'owo elomiran,
A si wa pada fi sa o l'ogbe.

2. A jaja gbe o si ipo agbara,
O bere si fi ipo na se 'jamba f'elegbe re;
Ida ipo na le bo sowo elomiran,
A si wa pada fi sa o l'ogbe.

3. A jaja fun o ni opa agbara,
O bere si f 'opa na se 'jamba f'enikeji re;
Opa agbara na le bo sowo elomiran,
A si wa pada fi se o l'ose.

4. A jaja fun o ni gege agbara,
O si fi gege na se 'jamba f'aladugbo re;
Gege agbara na le bo sowo elomiran,
A si wa pada fi sa o l'ogbe.

5. A jaja fun o ni oruka agbara,
O bere si fi oruka na gba 'ju ota re;
Oruka agbara na le bo sowo elomiran,
A si wa pada fi se o l' ose.

6. A jaja fun o ni fila agbara,
O si fe ma fi fila na se 'jamba f'elegbe re;
Fila agbara na le bo sowo elomiran,
A si wa pada fi se o l 'ose.

Nje nitoto nigbati e ka awon ese aşaro yi tan ni ikokan, e ko ri ogbon ko nibe? Ni ojo ti emi AKOW E ka a, mo ronu jinna pupo o je ki n t u n se i p i n n u pe ko si iru ese ti enia kan le se mi ti nko ni darijin in.

Bi oro asaro ti ALUFA ATILADE pe ni "MA FI IDA NA ŞE JAMBA" ti ko awon omo ile-iwe ni ogbon to ni o tun se ikilo fun baale ile, iyawo ile larin oregun, iwo oga ibi ise ti o nse ikilo ati iwo oselu ti a fi eeku ida ase le lowo ti enikan ko le foju kan o mo.

Opolopo awon akowe atata (Authors) ni agbaiye, awon ojogbon akewi (Poets and Philosophers) ni ile awon alawo funfun ko se ju eyi na lo. O ye ki a jeki nkan ile wa jo wa loju. O ye ki a ma ra iwe Yoruba ki a si ma ka won, ki a ma fi won pamo fun omo wa fun itan lehin ola nitoripe awon gbogbo nkan ti a ko kakun lojo oni ni nwon yio di nkan itan ti ao ma fi owo ra lehin ola.

---

## Adajo Ju Afibisuolore Kan Sewon Odun Meje

BENIN CITY — Adajo-agba Kotu awon Olopa ni ilu Benin ju okunrin kan afibisuolore ti oruko re nje Owie Ebohon, eni odun marundinlogoji si ewon odun meje fun esun wipe o fole o si ji nkan ko nibe.

Ejo ti awon olopa ti nwon mu okunrin odaran na wa si iwaju adajo ba a ro ni wipe lojo kan o lo si ile obinrin kan ti awon npe ni Womiloju Thompson, nigbati o de ibe o ba omo obinrin na ti nwon ni Godwin nile, odaran na ni aburo Womiloju ni on.

O wole, o si joko o fun Godwin ni kobo meji pe ki o jowo ki o tete ba on fi ra iresi ni oja ki on le je nitoripe ebi npa on lati ibiti on gbe ti mbo.

Gbara ti omo na ti bo si ita ni ole yi ti wo iyara lo ti o si ko gbogbo aso ati golu Womiloju lo. Adajo ni afibisuolore ni olosa na.

# ELETI—OFE

A NJUWKO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO.960 SATURDAY MAR. 23th–MARCH. 29th 1963


# Otito Oro Bi Isokuso

Inu awa onfwe irohin ELETI-ỌFẸ dun pupọ lati gbọ ọrọ ti Ọgbẹni Fani–Kayọdọ tiṣe igba keji Olotu Ijọba tuntun Ipinlẹ Iwọ Orun sọ, nigbati nwọn nṣe aṣeyẹ idagbere fun Oyinbo Ajẹlẹ kan ti orukọ rẹ nje Percy Dyson ni Abẹokuta ni ọsẹ ti kọja lori eto OWO OJULE (Tenetment Scheme) ti o fẹ fi igba kan da tulasi silẹ larin awọn Ẹgba.

Ọgbẹni Fani–Kayọde ni gẹgẹ bi ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ ALAKUKỌ (N.C.N.C.) alatako ni on jẹ fun eto owo-ojule ti awọn kan gbe jade fun ilọsiwaju ilu Ẹgba nigbana, on ko mọ wipe eto ti o jinna daradara ni eto na.

Nitotọ eto owo-ojule yi ti sọ Ijọba ibilẹ Ẹgba di olowo ati ọlọrọ ṣugbọn nigbati nwọn fẹ gbe e jade siwaju awọn ara ilu ni iwọn nkan bi ọdun mẹrin sẹhin ko si ebu ti nwọn ko bu awọn ti nwọn lọwọ ninu eto na tan nigbana.

## Maje–Ko–Baje

Awọn kan ninu awọn ọmọ Ẹgba ti nwọn ko fẹ ki nkan bajẹ ni ilu Ẹgba dide sọrọ na, nwọn na owo, nwọn na ara lati la iru anfani ti o wa ninu eto owo ojule na fun awọn ara ilu wọn, ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti o jẹ alatako nkona mọ wọn nidi pe ki nwọn fi aake kọri, ki nwọn mọ gba a rara.

Awọn Ẹgba ti nwọn mbẹ loko ni na ọrọ ko kan awọn lọwọ, nwọn ko mọ wipe o kan awọn lẹsẹ ati lori papa awọn agboko-roṣu inu wọn ti wọn kọ pẹtẹsi jankan jakan si arin igboro Abẹokuta ti nwọn ko fẹ de ibẹ mọ. Awọn na si ngbọ irohin bi ilu Yoruba miran ti nwọn ko gbajumọ to ilu Abẹokuta ti ndi ỌLANREWAJU lojojumọ.

Diẹ lọku, ilu Ẹgba fẹrẹ di ẹni ẹhin lori eto owo-ojulẹ yi. Ṣe ẹnyin na wa ri pe OTITỌ ỌRỌ BI ISỌKUSỌ lori.

# Iwe Si Olotu

## Eniti O Ba Yo...

Olotu, Mo gba fun otitọ ọrọ ti ẹ sọ fun awọn oṣelu alakoso ilu wa ni ọsẹ ti o kọja lori owo ọgbọyi ti awọn ara ilu awọn fẹ fi ta tẹtẹ ẹsẹjija ti eni ko ba oju mu rara. Mo gbedi fun yin!

A nki i, a nsa a bayi awọn alakoso Ijọba wa ni awọn ko ti mọ ẹniti o jalaisi. Ṣe nwọn ko mọ wipe ebi ati iṣẹ ọpọlọpọ wa fun awa ara ilu Nigeria ni nwọn ṣe nfi owo tafala bayi.

A nfẹ ki nwọn gbẹ omi-kanga fun awọn ara wa ti ko ri omi mu ni igberiko kakiri pẹlu nkan alafia miran bi ile-egbogi fun agbegbe ti nwọn ko ni. Nkan ti a fẹ niyi, a ko fẹ ki a mọ fowo tafala niwaju awọn Oyinbo ti nwọn ti to tan.

Igbobi, Yaba

Eni ni Kọlawọle

## E ye mu Moto lori ere

Ẹnyin ọmọ ile-iwe mo fi ikunlẹ abiyamọ bẹ nyin pe ẹ ye fo mọ moto mọ lori ere lọjọ kan nigbati mo mbọ lati Ebute-metta ni mo ri awọn ọmọ ile iwe ti nwọn fo mọ moto akero (Bus) lori ere, ohun iyalẹnu ni o jẹ fun mi pe awọn ọmọ ile-iwe nfo moto Boọsi lori ere, ohun iyalenu ni o jẹ fun mi pe awọn ọmọ ile iwe nfo mọ moto Boosi lori ẹru si ba mi pupọ, mo si ranti ikunlẹ abiyamọ.

Mo gba ẹnyin ọmọde paapa ni imọran pe ki ẹ ṣọra ki ẹ ye fo mọ moto mọ lori ere Ko dara o.

Ebute Metta

Eni ni Latinu Babalọla

## Akowe Ilu Ajoji Fun Gesi



Ọgbẹni Duncan Sandys (on ni o wa ni apa osi) akọwe fun awọn Ilu Ajoji ti o mba Gẹsi ṣe ni o wa ninu aworan yi nibi ti o gbe mba Ọlọla Ṣeyyid Abdualla, Ọba Zanzibar sọrọ ninu Afin Ọba na. Awọn ara ilu Zanzibar nfẹ ominiran fun ilu wọn ni kiakia.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## (Lati Owo Ayiluka)

### Mo–Ba–E–Yo

Lati igbati Ọlọla Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto ti fi bi apara bi apara sọ fun awọn ara rẹ nile ikbimọ ni Kaduna wipe awọn jandaku kan ti fi "wosika" iku ranṣẹ si on yio lọ nitoripe awọn fẹ pa on, ko si ẹniti ko fi iwe mo–ba–ẹ–yọ ranṣẹ si i tan afi emi Ayiluka.

Iwe mo-ba-ẹ-yọ na bẹrẹ lati ọdọ awọn oṣelu wa, awọn jẹ-nrile-gbe paapa kò ti wọn, awọn ẹru-ọba nu asọ leka lati Funtua, Ọusau, Sokoto ati agbegbe rẹ wa si Kaduna lati wa ba a ṣe ibakẹdun; ṣugbọn Kilotoyi? Kilode!

### Omo'Ba Sokoto

Gbogbo rẹ leju emi Ayiluka dabi ifẹ OJULARI. Lati igbati emi ti nkọwe mi ta fun awọn araiye, iru iwe-ebu ati iwe-ọjọ-iku bayi ti mo ti gba ko ni iye; nigbati mo ba nwon ọrẹ mi sọ ọ ẹrin ni nwon nfi mi nrin ko si alabadaro, ko si ẹniti o tẹ waya mo-ba-ẹ-yọ ranṣẹ si mi.

Sardauna, ọmọ Ọba Sokoto, emi Ayiluka paada ba nyin yọ; ṣugbọn iku ti yio pani jinna si i ni ọrọ na, ṣugbọn kotoyesi ni a npe iru awọn iwe bayi,

### Iku Di Kobo

Mọ gbọ wipe Adajọ Sowẹmimọ paapa ti gba iwe ọjọ–iku lati ọwọ awọn janduku Shomolu l'Eko; iwe-ebu ati egun ni adajo–agba ilu Ibadan kan ri gba lati ọdọ "lọya" janduku kan. Ko si ibiti awọn janduku ko si, nwọn wa ni ilu Oyinbo, nwọn wa ni Kano, Kaduna, Enugu ati Onitsha.

Ojo–okunrin ni o nka iru iwe bayi si; ṣe ẹnyin na gbọ ọrọ ẹtẹ ti Adajọ Ṣowẹmimọ bu lu ogunlọgọ iru iwe bẹ ti o ni on ri gba lososu. Akin ni awọn ọmọ Ẹgba, eleyi si mu mi ranti orin akin kan ti a mo nkọ l'Abẹokuta ti a ba nlọ gun Oko Olumọ tente:

B'ẹru ba mba yin ẹ wi o!
Ẹru ko b'ọmọ Ẹgba o;
B'ẹru ba mba yin ẹ wi o!
Ẹru ko b'ọmọ Olumọ.

Ọrẹ mi, iku inu iwe ti di kọbọ–kọbọ nisisiyi, awọn ọlẹ enia lo akọ wọn, awọn alainikanṣẹ lo nka wọn si.

### Oke 'Badan

Ije ni ọdun OKE 'BADAN ni Ibadan; ọdun na dun jọjọ bi o tile jẹ wipe nkan kọ lọ dede bi ti atijọ ni ilu Lagelu. Awọn ọmọ ati agba-lagba tẹle abọ'ke chin. Orin wọn ti ọdun yi yatọ pupọ. Iwọ na gbọ kan ti nwọn nwi.

Ẹ ma ba mi wi,
Aboke ni jmo ba lọ:
Ka rowo iyan,
Aboke ni mo ba lo;
Kaiye ko roju,
Aboke ni mo ba lọ;
Olọwọ Aro,
Aboke ni mo ba lọ.

Ọdun Oke 'Badan na yio gba gbogbo wa o–Amin. A ko ni ku iku bọmbu, a ko si ni gba iwe ọjọ-iku lati ọdọ awọn janduku ni Ogunpa Amin.

### Tayi, E Ku Ewu

Ọrọ ọmọ jankato jankato! Ni ọsẹ ti o kọja yi ni mo ba awọn ara wa meji kan yọ ayọ ọmọ tuntun ti iyawo wọn ṣẹṣẹ bi; ni Tuesday ijarun ni arabinrin wa kan, Tayibatu Oshodi bi ọmọbinrin kan fun baale rẹ, Ọgbẹni Agoro. Emi Ayiluka sọ oruko ọmọ na ni MORẸNIKẸ. Ẹbi a ron nkẹ, ọrẹ a ro nkẹ; Ọlọrun yio si da ọmọ na si, a ni ọwọọ lẹhin. A ki awọn ẹgbọn rẹ, Iya Kari ati awọn alaṣo ni Erelo, nwọn ku orire.

# Olowo Kan Kan Oko Sere-Sere



Ọgbẹni Olowo kan ni ilu Gẹsi ti orukọ rẹ nje Percy Shakespeace ni o joko ni apa osi ninu ọkọ reluwe ṣere–ṣere kan ti o ra lati ma fi ko ọmọde ati agbalagba ninu ọgba rẹ nitori owo iranlọwọ ti nwọn fẹ ṣe fun awọn afọju ilu Afrika Ọkẹ mẹrin o–le ẹgbaka ponun (£100,000) ni owo ti nwọn nfẹ fun iranwọ awọn afọju na.

# Obinrin Ara Congo Ni Ilu Oyinbo



Aworan Obinrin ara ilu Kongo (Congo) nibiti o gbe ti nko bi nwon se nko awon omode ni iwe ni ilu Oyinbo.

SHEFFIELD — Ọrọ ẹkọ kişe yẹyẹ r a r a nibikibi, olukuluku ni o nwa ilọsiwaju fun orilẹ ede rẹ, iyen ni ti arabinrin kan ara ilu Kongo (Congo) ti orukọ rẹ nje Madam Binton, ti o ba ọkọ rẹ lọ si ilu Oyinbo laipẹ yi.

Nigbati o de ibẹ, o ni on yio fi oko kan pa ẹ.yẹ meji—işẹ anu ti on nşe ni ilu on, on a wa ilọsiwaju işẹ na lati kọ bi nwọn ti nkọ awọn ọmọde lẹkọ ni ilewe ilu Oyinbo.

Eleyi mu u lọkan pupọ ti o fi bẹrẹri ba awọn ọmọ Gẹsi şe ọrẹ titi ti nwọn fi mu lọ si ilewe awọn ọmọde kan ti nwọn npe ni Hemsworth Primary School ni ilu Sheffield--aworan rẹ ni ẹ nwo ni apa osi iwe yi nibiti o gbe ti nkọ bi nwọn ti nkọ awọn ọmọde lẹkọ.

Bi on ti nşe evi ni baale rẹ ti o ba wa si ilu Oyinbo paapa nlọ si ibi işẹ awọn awa-edu nitoripe ọga işẹ ni o jẹ nibiti nwọn ti nwa edu ni Katanga (Congo).

## Akiyesi

Gbogbo enia ti nwọn nwa ọgbọn ni nwọn nka iwe irohin Eleti–Ọfẹ. Iwọ na ma ka a ni ọsọsẹ; o kun fun irohin ilẹ Nigiria ati Oke–Okun.


Plug in to a

BRIGHTER

FUTURE . . .



And the best way of doing this is to take a life Insurance policy for yourself and children from those who are ready to help :-

Great Nigeria Insurance Co. Ltd.

(Incorporated in Nigeria)

Head Office: 39/41 MARTINS STREET LAGOS. P. O. Box 2314, Tel. 25251
Branches:- WRFC Building Lebanon Street, Ibadan; 151A, Folagbade Street P. O. Box 133, Ijebu-Ode; Telehone 82 Ibara Road Abeokuta.


## Awon Oyinbo Ri Awon Iran Tuntun Kan Ninu Igbo

( O bẹrẹ lati oju ewe kinni )

IKOKO — amọ ni awo ti nwọn fi njẹun, awọn funra wọn ni nwọu si fi ọwọ ara wọn mọ wọn. Ewebẹ odo ati awọn ẹiyẹ oju omi ni nkan ti awọn enia nwọnyi njẹ lojojumọ.

Ọbẹ atijọ ti awọn alagbẹdẹ aiye igbati oju ko ti la şe ni nwọn ba ninu ahere ti gbogbo wọn ngbe tọmọtọmọ.

Ile ti awọn enia na ngbe ma daradara, awọn irin ti o ti dogun ti nwọn ba ni inu ile wọn jẹ awọn ti nwọn ri şa ninu igbo lara awọn ọkọ ofurufu awọn ṣọja Jepani ti nwọn ja lulẹ nigba ogun Jamani, ninu awọn wọnyi ni nwọn pọn, ti nwọn fi nge nkan ti nwọn nlo ninu ile wọn.

Yẹri oni-iko ni awọn obinrin wọn nsan mọdi, ihoho ni awọn ọmọ wọn ọkunrin nrin kiri.

# Nigerian Nutrition Students In London

LONDON–Five Nigerians now studying in London are among the 22 overseas students who are studying food science and applied nutrition, on a course arranged jointly by the London School of Hygiene and Tropical Medicine and the University of Ibadan, Western Region.

The Nigerians are: Mr. J. A. Olusanya, Principal Health Education Officer, Health Education Unit, Ibadan: Miss Florence Ogunsulere, Teacher of the Domestic Science Centre, Lagos: Mr. G. O. Uwuaemelulam, of the School of Hygiene, Aba: Mr. A. T. Hamza, of the Medical Field Uuit, Makurdi: and Mr. O. Ibidunni, House Education Officer, Federal Ministry of Health, Lagos.

The course will last eight months — four months in Britain followed by four in Ibadan. Fifteen countries incluaiag Britain are represented on the course, which will be an annual one, from March to October, until 1967. The United Nations Children's Funds (UNICEF) has undertaken to provide £221,000 for the five years period.

## Sierra Leone Teacher On Domestic Science In Birtain

SUSSEX — A Sierra Leonean teacher, Miss Agatha Lewis, from the Cathedral Boys School, Freetown, is taking a one-year domestic science, course at the Seaford Training College of Housecraft, in Sussex. There are 17 overseas students on the course, who also work closely with the London School of Hygiene and Tropical Medicine.

## York's " Zanzibar Week' Eucourages Sale Of Cloves

YORK — The city of york, England, which is trying to establish a permanent link with Zanzibar has been encouraging the sale of Zanzibar cloves with a display of pomanders-clove oranges as part of an exhibition, during Zanzibar week in the city.

The people of York are also trying to raise funds to encourage rice growing on the island.

## Special British Truck For Tanganyika

LONDON— A huge truck, costing £5,800 and specially designed for hauling heavy mchinery, will shortly be leaving Leyland Motors the Lancashire vehicle manufacturing firm, for Dar-es-Salaam, for operation with Tanganyika's Department of Water Development and Irrigation.

The truck which will haul a low-loading trailer between project sites, is powered by a 150 h p. diesel engine, has power-assisted steering and a six-speed gear box.

## Africa's First Internal Course For Journalists

NAIROBI — Tom Hopkinson, British former editor of "Drum" is the director of the first international training course for jounalists in Africa, which was inaugurated in Kenya on Monday by the Governor, Mr Malcolm Macdonald.

Fifteen students from seven counries are taking the first six-months' course sponsored by the international Press Institute, which has as members editors and managers of more than 600 newspapers in 48 countries.

A second centre is to be set up in West Africa, Mr. Hopkinson said in Nairobi, and he hoped that within four years 100 jounalists would be taking such a course each year at the two centres.

## London Memorial Service For Late Bishop Of Lagos

LONDON — A memorial service for the late Right Rev. Adelakun Williamson Howells, Bishop of Lagos since 1955, who died on 7th March, will be held in London on 1st April. The service will be held at St. Martin-the-Field's in Trafalgar Square the church known to many West African visitors as "the Commonwealth Church".

The Vicar of St. Martin-in-Field's, the Rev. Austen Williams, will take the service.

## New British Ambassador To Liberia.

LONDON — The Queen has been graciously pleased to approve the appointment of Mr. M.T. Walker to be Her Majesty's Ambassador and Plenipotentiary to Liberia, is annouced today.

Mr Walker will succeed Mr. H A N Brown, C V O,, who will sortly take up an appointment in the Foreign Office.

Mr Walker, who was born in 1915, has served in British overseas missions in the Middle East, in Honor and in Saville, Spain,

## The Late Herbert Macaulay



The Doyen Of Nigerian Politics

## Enahoro Di Egungun:

# Nwon Nmu Padabo Wa Si Nigeria

LONDON — Ọrọ Oloye Anthony Enahoro, igbakeji baba ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ti awọn alaṣẹ ilu Gẹsi ti aṣe wipe awọn fẹ da pada si ilu Nigeria ti de gongo nisisiyi nitoripe awọn kan ninu ile igbimọ wọn (House of Commons) ti fi aake kọri wipe ko yẹ ki awọn da a pada wa si Nigeria nitoripe nwọn a fi iya jẹ.

Nigbati awọn igbimọ na tun pade ni alẹ ijẹta akọwe ilu Gẹsi lori eto ilu, Ọgbẹni Henry Brooke ni on ko fẹ yi ọrọ on pada mọ lori wipe aṣẹ ti on ti pa wipe ki nwọn da Oloye Enahoro pada si ilu Nigeria lati lọ jẹ ẹjọ ti nwọn nwa fun.

Ọgbẹni Brooke ni on ti ri irohin kan gbọ lati ọdọ awọn alakoso ilu Nigeria pe nwọn ko ni fi iya kan jẹ Oloye Enahoro ti o ba pada si ilu na; nwọn ni awọn ko ni tako lọya Oyinbo ti o ba fẹ ki o wa ba on ṣe agbẹjọro ọrọ na.

Ju gbogbo rẹ lọ awọn Igbimọ ile aṣofin ni ki nwọn si da Oloye Enahoro duro na titi di ọsẹ ti mbọ ki awọn le ri aye sọrọ lori ọrọ rẹ na ki awọn si dibo le e lori.



Boya nwọn le mu u wa si Nigeria ni ọjọ mejo loni; ṣugbọn o da wa loju wipen wọn nmu u bọ wa sile.

## Malu Kan Bu S'ekun Lori Oku Ekeji Re

POOJAB (India) Iṣe, nia niṣe ẹranko, oriṣiriṣi nkan abami ai a ngburo ni aiye isisiyi; irohin kan ti a gbọ lati ilu Poojab ni India ni ti malu kan ti o bu si ẹkun ti o si nhu bi ẹda ọmọ enie nigbati o ri oku abo malu ti ton pẹlu rẹ jọ ngba pọ nibiti o gbe ku si

Lati nkan bi ọdun mẹwa sẹhin ni Olowo malu na ti nsin wọn. A-ṣẹ-malu si ni awọn ma u mejeji na si jẹ fun ṣugbọn nigbati Ọlọjọ de, o mu ọkan lọ ninu awọn malu na.

Gẹgẹbi aṣa ilu na, nwọn sin oku malu yi bi oku enia abẹda nitoripe nwọn ki jẹ malu ni ilu India, bibọ ni nwọn mbọ wọn bi oriṣa.

## Ijoba Fe Gba Ile Awon Egbe Onisowo Kan

IBADAN—Ninu ikede Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun kan ti o jade ninu ọsẹ yi awọn Alakoso Ijọba Ipinlẹ na ṣe ikede wipe awọn ti ṣe eto pari lati gba awọn ile kan ti awọn ẹgbẹ onisowo kan fi owo gọbọyi kọ si ọna onigbogbo ni eti Ikẹja ti nwọn npe ni Maryland Estate ti orukọ awọn ẹgbẹ na njẹ Shonny Investment and Properties Company Limited nitori gbese ti nwọn jẹ awọn ẹgbẹjọda ti Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ọga awọn ẹgbẹ onisowo na, Ọgbẹni S. O. Shonibarẹ, ni owo awọn ẹgbẹjọda kọ ni awọn fi kọ awọn ile na, awọn ya owo lọdọ awọn banki kan ni. Nwọn si ti pe ara wọn lẹjọ lori ọrọ, na si Kotu.

# E Ku Abo!

**Aworan ti e nwo yi ni igbati omo kekere ara ilu Fiji kan ti nwon npe ni Adi Kaunilotuma nki Oba Obinrin ilu Oyinbo nigbati Oba na lo si ilu Fiji ni aipe yi. Gege bi asa awon ara ilu Fiyi ti odomode ba nki agbalagba o ni lati di owo re mejeji ni, bena si ni omo yi se nigbati o nki Oba na.**

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street Lagos Box 467 Phone 23370 Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.